**LAKAYE ORO**

KI ife ki o wa laiṣetan, Ẹ takete si ohun ti iṣe buburu, Ẹ fi aramọ ohun ti iṣe rere.

BIKOṢEPE Oluwa ba kọ ile na, awọn ti nkọ o nṣiṣẹ lasan; bikoṣepe Oluwa ba pa ilu mọ, oluṣọ ji lasan.


# Irohin Yoruba

NO. 783 — JUNE 8 — JUNE 14, 1960 — Kobo Meji (2D.)


**OWE**

Bi a ngun iyan ninu ewe, bi a nse ọbẹ ninu epo ẹpa, ẹniti o yo yio yo.

A ki i ru ẹran erin lori, ki a ma a fi ẹsẹ tan ibo irẹ.

# AJA GBE BEBA KỌRẸNSI M'ẸRAN, ALAPATA DA ỌJA RU

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ni ariwo nta ge e ni arin ọja Mushin nigbati gende fọn-fọndofọindo kan ti nwọn npe oruko rẹ ni "Ayinla Alapata nle aja ti o gbe beba korẹnsi ponun kan hanu pẹlu egun ẹran lati iso de iṣọ ti o si kigbe to o pe, ẹ dakun ẹ ba mi gba korẹnsi lenu aja yi nitori Ọlọrun "temi ni! temi ni!!" nibiti o ti nle aja ni kakiri larin ọja Mushin, nse lo digbolu iya agba ti o kiri egbo lati abule Isaga wa tà ni Mushin, o si fọ ọ ni koto. Bi o ti nle aja na lọ, ni iya elegbo paapa nsure tele alapata yi pẹlu igbe tantan lenu pe ẹ dakun ẹ ba mi mu okunrin yi, ẹ ma jeki o salọ, o fọ mi ni koto egbo! o fọ mi ni koto egbo, oro o!!

Opelope okunrin Hausa kan ni o na aja na ni opa: beba korẹnsi ponun kan pẹlu egun ẹran ti o gbe hanu si bọ silẹ, were ni Ayinla Alapata he beba korẹnsi ponun kan ati egun ẹran na. Bi Ayinla Alapata si ti nyi padà ni iya elegbo ndiro mọ lati gba owo koto egbo rẹ ti o fọ, ni kukuru awọn enia ti o pejọ le wọn lori bere idi abajọ. Iya elegbo ni o koko rojọ, o ni jẹjẹ ni mo nkiri egbo mi larin ọja Mushin ki ọkunrin tanbọnrin tanbọnrin yi to kolu mi lati ẹhin wa, mo doju delẹ, mo si yi ogbiri gbiri koto egbo mi si fọ o danu. Eyiti okunrin yi iba si fi duro sajo mi nṣe ni o nsalọ ni mo ba nsare tẹle titi ọwọ mi fi tẹ ẹ, oro temi kọju be lọ, mo faramọ ti apa ati ẹsẹ mi ti mo fi bo yanmayanna ṣugbọn ngo gba owo egbo mi yio pe perepete.

Awọn ondiaja si tun doju-ko Ayinla alapata, nwọn ni ki o ro ẹjọ tirẹ bi o ba ti ri. O ni ẹṣe pupọ ẹ ku atunṣe o, Oluwa ko ni jeki ẹ ri ayalu bi ti emi yi o. Gbogbọ nwọn ni aṣe. O ni obinrin kan ni o wa ra asameegun oni sile meta lọwọ mi, o si san beba korensi ponun kan fun mi, mo si fi owo osi fi le ori tabili ti mo ti nta ọja, a ṣe ategun ti fẹ beba korensi ponun kan bọ si abẹ tabili ti mo fintaja nko mo, nigbati mo ko senji sile meta-dilogun sile fun obinrin yi tan, nle ki nnawọ mu beba ponun kan ti mo fi le ori tabili ti mo fi ntaja, awati ni mo fi ṣe.

Iti mo si ti npeyi ranin-ranin, ti mo si nkigbe pe, ẹ gba mi o, nibo ni beba korensi ponun kan ti mo fi le ori tabili yi ha bọ si? awọn ti a jijọ so si ibi kan-


**Wo oju ewe kerindinlogun**


# Ọdun Ileya dun l'Eko

EKO.

NI ojọ Aiku ti iṣe ojọ ka-ran oṣu yi ni awọn Musulumi kirun ọdun Ileya. Nigbati ọjọ ọdun na ti ku ọla ni nwọn ti bẹrẹ aisun ọdun ti ilu ọdun lotun-losi kakiri ile awọn elọdun na, bi nwọn ti njo ni nwọn nfi jijẹ ati mimu panu titi ile fi mọ.

Nigbati ilẹ si mọ, gbogbo wọn si ti bẹrẹsi i gbaradi a ti lọ kirun "Idi" ni ẹhin odi. Nwọn bẹrẹ tito lọ yi lati agogo mejọ owurọ, nigbati yio fi to agogo mejila, nwọn ti kirun tan ti gbogbo wọn si ndari bọ wa le.

Oriṣiriṣi aṣọ olowo-iyebiye ni gbogbo wọn wọ, awọn miran wọ mọto ayokẹlẹ, awọn miran ṣa ara wọn jọ sinu mọto akero, awọn miran gun keke-alupupu, awọn miran gun kẹkẹ-ologere ati awọn ogunlogo awọn ti o nfi ẹsẹ rinbọ wale ko ni onka.

Olukuluku wọn si tele dari wa sile lati wa a pa


WO OJU EWE KEFA




Eyi ni aworan yi ni igbati Alfa Liadi Alade Ibrahim, Lemọmu-Agba, Eko nke Tira ọdun fun Musulumi Eko ati agbgbe rẹ lẹhin ti nwọn Kirun tan ninu Ọdun Ileya yi ni Mọsalais Idi ni Ọbalende

# Egbẹ Alakukọ tun fẹ fi awọn fọle-fọlu jagun fun idibo

IBADAN.

NI ọjọ Ojobo ti ise ọjọ keji oṣu yi ni asiri ipade ikọkọ awọn Egbẹ Alakuko (NCNC) tu. Imọran ti nwọn nda ni pe, ti aseko idibo ba sunmọ-etile, ki awọn gba ogun awọn fole-folu Naijiria jọ, ti nwọn ko ba to, ki nwọn ranse si awọn fole-folu ti o ba wa ni Oke-Okun (Ghana) ki wọn wa baawọn gbogun ti awọn ti ko ba je ti awọn ni aseko idibo wọle Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun.

**OSHUNRẸMI BINU FI ẸGBẸ ALAKUKỌ SILẸ**

Ogbeni Ayọ Oshunrẹmi ti o ti jẹ Alamojuto Egbẹ Alakuko (NCNC) Field Supervisor ti o ngba ẹtale-legbẹta ponun (£650) lọdun fun iṣẹ egbẹ oṣelu na, ti binu fi Egbẹ Alakuko na silẹ o si wọ Egbẹ Afẹnifẹre ki okan rẹ le wa ni alafia lati ṣe kilo-kilo fun gbogbo enia


(Wo oju ewe kokanla)

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

# Ọmọbirin kekere kan ṣeeṣi mu ọti ku

WARRI.

NI aṣalẹ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu ti o kọja yi ni Skinn Road ni ọmọdebirin kekere kan Kugbere Asagba ọmọ ọdun meji ku lẹhin ti o lọ ṣeeṣi mu igo ọti lile kan ( a bottle of gin) tan patapata.

Bayi ni ọrọ na ti ṣe jẹ. Nwọn ni ebi ni o le ọmọde yi bọ lati ọja nigbati o sin iya rẹ lọ ra nkan ọbẹ. A ṣe gbogbo bi iya ọmọde yi ti nseonje ni ile-idana nṣe ni Kugbere lọ si koro iyara ti o lọ gbe igo oti yi ti o si da a de ẹnu. Bayi ni o ti ṣe mu oti yi tan bamubamu. Ko pẹ lẹhin eyi ni ọmọde yi ba ṣe alaisi.

Pẹlu omijẹ kikoro loju ni iya ọmọde na fi nsọ fun awọn onirohin wipe on ti fi ẹtẹ, ninu oti lile yi to ọmọ on lẹnu wo ki awọn to lọ si ọja ni.

## Iya Ẹgbẹ Ijọ Aguda sin Mopelọla fun Ọkọ

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ karun oṣu ti o kọja yi ni iya Ẹgbẹ Ijọ Aguda (Roman Catholic) Ilia-Odo sin ọmọ rẹ kan Juliana Mopelọla fun ọkọ. Iya ati baba ọmọ yi fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ wọn lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni J A Ọdẹyẹmi, Kofo, M. Ayọ Orisabunmi, E. O. Adenihun Oyediran ati ọpọlọpọ awọn enia.

## Ikomọ Adeyẹmi dun, o larinrin

AKURE.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kini oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Ezekiel Adewuyi Adeyẹmi ṣe ikomọ ọmọ rẹ ti Ọlọrun fi ta on ati iyawo rẹ lọrẹ. Ọgbẹni J Bamkẹfa ni o ṣe alaga aṣẹyẹ ikomọjade na. Gbakeji rẹ ni Ọgbẹni Joseph Morakinyọ. Baba ọmọ na si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ rẹ lọrun.

Ọpọlọpọ awọn gbajumọ ati enia pataki ni o pese sibi aṣẹyẹ ikomọjade na.

Ki Oluwa ki o fi rere kari wa o.

## Oloye Shangowoye Alawẹ jade l'aiye

IREE.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu karun ọdun yi ni Oloye Shangowoye ṣe alaisi ni deede agogo meje abọ irọle. Gbara ti Oloye yi ti ku ni awọn ọmọ oloku ti berẹ si inawo, ti awọn nṣe ti nwọn nṣe. Ajibade Ajagbe ni ọdọ ti o wa ba wọn fi kokoro ilu dara nibi oku na. Nwọn si lọ sin oku Oloye yi ni ọjọ keji ti o jade l'aiye.

Alufa Ijọ African Church Iree ti orukọ rẹ njẹ S. A. S. Abidogun ni o ṣe isin ikẹhin fun Oloye yi. Jacob Shangowoye ati awọn ọmọ oloku yoku fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn ti o wa lọrun. Baba ti o ku yi fi ọmọ mẹfa ati ọmọ-ọmọ mẹfa si aiye.

Ki Ọlọrun ki o tẹ ẹ si afẹfẹ rere o.

## Ikomọ ọmọ Akinsanya dun

OWODE.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹtadinlogbon oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Amos Abiọdun Akinsanya ṣe ikomọjade ọmọ-birin kan ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ, Ayọ Akinsanya lọrẹ.

Ọgbẹni Jacob Sobọyọn Akinsanya, ẹgbọn baba ọmọ jọjọlọ na ni o ṣe eto isọmọlorukọ, gẹgẹbi aṣa ọmọ ibilẹ, o sipin iyọ-Oyinbo, ẹja, orogbo, atare, obi abata, iyọ iṣẹbẹ fun gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lati fẹnu ba wọn, lẹhinna ni o wa sọ ọmọ na ni Ọlayinka Olubunmi Ọmọlabakẹ Akinsanya. Aṣẹyẹ ọjọ na dun o larinrin irohin ko to afọjuba ni.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn enia pataki alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni L A K Ogunmọju ati awọn aya rẹ; awọn Ọgbẹni N S Akeyọs, M. O. Akinsanya ati ọpẹlọpọ enia.

## Ẹniti o ji Siga gbe fi £30 tanran

IBADAN.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu ti o kọja yi ni Adajọ-Agba Kotu Kekere Ibadan ṣe idajọ pe ki odaran kan, Festus Osagie Ogedengbe lọ fi ogbọn ponun (£30) tanran si Kotu tabi ki o lọ si ẹwọn ọgọta ọjọ dipo rẹ nigbati o rojọ ti o si gba wipe on jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun ni Kotu pe o ji idi siga kan gbe.

Ẹjọ ti ọlọpa ti o ba odaran na ṣelọ ro ni pe ni ọgunjọ oṣu ti o kọja yi ni odaran na ji idi siga Consulate kan ti iye owo rẹ jẹ ponun mẹtalelogorin, ṣile mẹwa ati kọbọ mẹwa (£83. 10s. 10d) gbe ninu Ile-itaja "Co-operative ti Self-service" Ibadan.


## Ojo mba Basikulu rẹ jẹ!




JOHNSON'S
NU-CYCLE

REG HARRIS—Ologbon oga awon asare-ije basikulu gbogbo aiye fun odun merin—so wipe:—
Asehinwa-asehinbo, ohun-elo kan niyi, lati fi nu, lati fi dan, ati lati fi daabo bo basikulu—
JOHNSON'S NU-CYCLE ko ni mu emi basikulu re gun nikan, sugbon yio tun daabo bo ara re ati ewa re pelu, nitoripe o ndaabo bo ise oda ati irin-didan re kuro lowo erukuru ati ipata. Tete apejuwe ... Ma a fi ori-adanrin JOHNSON'S NU-CYCLE nu basikulu re deede ... Ma a fi basikulu re yangan nipa lilo JOHNSON'S NU- CYCLE.




a product of JOHNSON'S WAX research


## CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

### AKIYESI PATAKI

OOGUN Ẹda £1. 1s. Latanlatan £2. 2s., Jẹdijẹdi £1 5s. Anfani nla l'evi. Kọwe si ỌRẸLARU 56, Ọlọrunṣogo, MUSHIN.

### Eti rẹ melo?

IWE itan abalaiye ati ti iṣẹdalẹ ti o kun fun ọgbọn ati aṣiri igbega atijọ, ti o si nmu inu enia dun. Kọwe fun Iwe-itaja:—MANAGER Box 104 Ebute Metta, Nigeria.

### AKIYESI

6TH, 7th, 8th & 9th Books of Moses lede Yoruba £1. pere. A le ri ra ni 15, Araoti Street, Yaba Nigeria.

### MO JUBA AIYE

FUN ohun elo to jẹ mọ iṣẹ Ogboni ati ohun anfani miran. Fi Stamp oni tọrọ (3d. stamp) fun iwe Aiye Akamara. APENA, 75, Haastrup Street, Suru-Lẹre—Nigeria.

# ITAN IṢẸDALẸ ILU ỌFFA

## Lati ọwọ M. O. Awudẹrẹ, Surulere

INU mi yio dun pupọ bi Olotu ba le gba mi laye ki nṣọ itan ilu mi Ọffa si inu iwe Irohin Yoruba fun gbogbo aiye ka. Mo ti ka ọpọlọpọ itan iṣẹdalẹ awọn ẹya ilu ilẹ Yoruba, o si dun mọ mi pupọ, nitorina, mo juba gbogbo ẹnyin opitan ilẹ Yoruba ati paapa julọ, awọn baba wa, awọn agba opitan ilu Ọffa. Itan na lọ bayi —

Ni igba laelae, Ile-Ọyọ ni ọdọmọkunrin ọdẹ kan ti o tẹ ilu Offa do ti wa, o si jẹ aromọdọmọ Ọba Oranmiyan ti iṣe ọmọ Ọba Odua ni Ile-Ifẹ. Nigbati o dide ni Ile-Ọyọ ilu baba re, o ṣe ọdẹ titi de ẹba odo kan ti nwọn npe ni Malka t'o wa ni ọna ilu Irra. Offa ni ọmọ-ọba yi fi nṣe ọdẹ gẹgẹbi Ibọn. Ọfa si da a lọju ni tita pupọ ju awọn ọdẹ ẹlẹgbẹ rẹ lọ, atamatase si ni, ki i ta ọfa tirẹ ki o ma ba ẹranko nitorina ni gbogbo awọn ọdẹ ati ojulumọ rẹ ba fi npe e ni oruko alaje pe "Ọlọfa-gangan "lati Ile-Ọyọ wa.

Nigbati adape orukọ rẹ "Ọlọfa gangan" yi mọ ọ lara tan, ẹnikẹni ko ranti orukọ abisọ ọdẹ yi mọ rara, bẹ ẹ ni o si fi gbe orukọ kanṣoṣo yi de Odo Malka lọna ilu Irra nibiti o tẹ ilu Ọffa akọkọ do si. Nitoripe, ẹnikẹni ko mọ orukọ miran mọ ọdẹ ti o tẹ ilu yi do, ni nwọn ba kuku npe ilu rẹ nani "Ilu Ọlọfa-gangan", ṣugbọn nigbati oju awọn enia bẹrẹsi la si i, ti ilu yi si di mimọ fun gbogbo enia tan, ni nwọn ba kuku npe e ni "Ilu Offa" ni ede kukuru.

### NWỌN ṢI ILU ỌFFA LỌ SI ILỌFA

Nigbati ilu yi bẹrẹsi kun si i fun ọpọ enia ni nwọn ba tun ṣi lọ si ibikan ti nwọn npe ni "Ilọfa". Ṣugbọn ko pẹ pupọ ti nwọn tun fi ṣi kuro ni Ilọfa lọ si ibikan ti nwọn npe ni Ọfa-oro nitoripe ilẹ Ilọfa na ko ba wọn lara mu dada to. Ọfa-oro yi jẹ adugbo awọn ẹya iran Tapa, ṣugbọn nigbat awọn Tapa yi bẹrẹsi gbogunti wọn nigbagbogbo lati ko wọn lẹru ni nwọn ba tun ṣi kuro nibẹ lọ si ibikan ti a npe ni Ọffa-Irese ti o wa lẹba ilu Igbaja, nigbati ogun ko si tun jẹki nwọn ni ifaiyabalẹ nibe ni nwọn ba tun ṣilọ si "Ọffa-Ikoṣẹ".

### ỌLỌFA MU ADE ATI IPỌN MỌRẸMI WA SI ỌFFA

Ilu Ọffa-Ikoṣẹ yi ko jinna si ẹba ilu Ilẹmọna. Lati Ọffa-Ikoṣẹ yi ni nwọn ti sun diẹdiẹ de "Ilu Ọffa-Esun". Ọffa-Esun yi wa ni ọna "Ilu Irra". Ki ọdẹ ọlọfa-gangan ti iṣe ọmọ-ọba Ọyọ yi to kuro nile, o mu awọn nkan patakipataki ti iṣe apẹrẹ ọmọ-ọba dani lati fi han pe aromọdọmọ ọba Oduduwa ni on. Awọn nkan apẹrẹ ti o mu wa si Ọffa na ni Ipọn(tabi igbakọ) kan ti nwọn npe ni "Mọrẹmi" eyi ni nwọn si nṣe ọdun Edi rẹ ni igboro Ile-Ifẹ titi di oni oloni.

Awọn ade ti baba rẹ pin fun un ni o pin fun awọn egugun kan ti a npe ni "Ewulẹ" ati "Awodegbo" ni Ọffa, nitoripe awọn ọba ile Fulani ti ilu Ọffa wa labẹ rẹ ki i de ade, Lawani ni nwọn nwe, nigbati Ọba Ọlọfa na ko si gbọdọ de ade afi ki o we lawani, ni o ba kuku fi pin awọn ade rẹ fun awọn egungun ilu rẹ na, o si tun ni awọn iranṣẹ ti a npe ni Ilari gẹgẹbi awọn ọba alade ilẹ Yoruba yoku, gbogbo awọn nkan ti a darukọ yi ni o wa ni ilu Offa titi di oni-oloni.

### IWE ITAN ILẸ YORUBA JẸRI SI ỌFFA

Dokita O. Johnson, oniwe Itan Ilẹ Yoruba jẹri si itan iṣẹdalẹ ilu Offa ni oju ewe kẹrindilogorin page 76 bayi pe:—"Ọlọyọ ti Ọyọ, Onikoyi ti Ikoyi, Olugbọn ti Igbọn, Arẹsa ti Irẹsa, Onipetu ti Ipetu ati Ọlọfa ti Offa". Ẹ tun wo oju ewe ojidilẹgbẹta o le mẹrin (page 564) iwe kanna, ẹ o tun ri ẹri rẹ ka bayi pe:— "Ọlọfa je olori gbogbo awọn ọba ilẹ Ibọlọ ti o wa larin Ilọrin ati Iwo". Bi a ba si de igboro ilu Offa loni, a o ri agbo-ile ti a fi orukọ oba Ibọlọ sọ, nitori bi nwọn ba wa si igboro ilu Ọffa ninu awọn agbo-ile wọnyi ni nwọn ma a nde si.

Diẹ ninu orukọ awọn agbo-ile wọnyi ti o wa ni igbooro ilu Ọffa loni ni:— Ile Olokuku, Ile Ọlọyan, Ile Onira, Ile Ẹlẹmọna, Ile Onigosun, Ile Arẹ ati bẹẹ bẹ ẹ lọ. Bi a ba si fi oju wo awọn ilu nlanla ti o wa ni ilẹ Yoruba loni, ko si ilu ti Offa ko ni adugbo tirẹ ninu rẹ nibẹ. Ni Abẹokuta, adugbo Ọffa ni Ija-ọffa, ni Ibadan, adugbo ti Offa ni Oke-Ọffa.

### ARỌMỌDỌMỌ ODUDUWA

Bi enia ba wo ilu kan ninu awọn ilu ẹku ilẹ Yoruba, ti ko ba si ri adugbo Ọffa nibẹ, ṣugbọn ti o ba gbọ ti nwọn ba nki ara wọn ni oriki wipe "Iyẹru-okin, Ọlọfa, ọmọ la a re ki o dọgba" tabi "Ọmọ-ọlalomi" gbogbo iwọnyi fi han pe, dajudaju, awọn ọmọ Ọlọfa ti iṣe arọmọdọmọ Oduduwa ni awọn ti o wa nibẹ ti nwọn nki ara wọn na, o si tun fi han gẹgẹbi ilu Ọffa ti tobi to ati bi o ti gbooro to ni awujọ awọn ilu ilẹ Yoruba.



Aworan yi ni ti apapọ awọn ọba ati awọn Oloye ti Ile.iṣẹ Erọ Radio Alaworan (Television House) ya nigbati wọn wa bẹ Ile-iṣẹ na wo ni asiko Ipade Igbimọ awọn Ọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti nwọn ṣe kọja laipẹ yi ni Ibadan

## Ileya

(Lati oju ewe kini)

ẹran-Ileya, lẹhin ti nwọn pa ẹran Ileya ti awọn iyawo wọn nṣe ọlọjọjọ a ti tu ifun ẹran ati lati din in, ni awọn ọkunrin tun mba faaji ajọyọ ọdun lọ ninu palọ ati ọdẹdẹ wọn, awọn miran si ta atibaba si ita ti nwọnnṣe faaji ninu rẹ.

Lẹhin ti awọn obirin ti ṣe ọpọ ifun ẹran dindin tan ni nwọn wa a tun ngbe wa ninu awo fun awọn ọkọ wọn lati ma a fi panu ṣe faaji, eyi ni nwọn nṣe titi di aṣalẹ. Ni aṣalẹ ni nwọn tun bẹrẹ ere titi ti nwọn tun yi si aisun ti nwọn si ṣe e di ọjọ keji.

Ọdun na dun to bẹ ẹ gẹ ẹ ti o fi jẹ pe aye isinmi ọjọ meji ti Ijọba yọnda fun ti ọdun na ni ọjọ keji ati ọjọ kẹta ọdun nṣe ni awọn gbajumọ ati bọrọkini ilu Eko tun lo ọjọ na bi ọjọ ajọyọ Ọdun Ileya gangan.

Aṣeyi-ṣamọdun, ọdun a yabo o.

Ẹ ma a ka Iwe

IROHIN YORUBA

nigbagbogbo fun irohin aladun

# Ọmọ Ẹgbẹ Olomi jẹbi ẹjọ idibo ti o pe ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre

# Ọkunrin kan bu obirin jẹ



# Fi Warakaşi Kraft pese onjẹ daradara kiakia




**KRAFT** FOODS LIMITED
Regina House, Marylebone Road, London N. W. 1.




# Ayọrisi Idije Orire Ijọba Ipinlẹ Iwọ - Orun

**Awọn enia ti o jẹ owo gọbọi ninu idije ori're ti Ijọba Iwọ-Orun ṣe ni ọjọ Kejidinlọgbọn oşu ti o kọja yi ni gbongan Apejọ Mapo Ibadan ni Dele Awodọla ti 2A Beecroft Street l'Eko ni o ṣe orire jẹ ẹbun kini ti owo rẹ jẹ £3,000. Ẹniti o ṣe orire jẹ ẹbun keji £2,000 ni Olajide Ogunfowode ti Ijẹbu-Igbo. Ẹniti o ṣe orire jẹ ẹbun kẹta £1,000 ni Olanrewaju Sunmọla ti 18, Alagbeji Court, l'Eko.**

### Awọn ẹnikọọkan ti o ṣe orire jẹ £50

### Awọn ẹnikọọkan ti o ṣe orire jẹ £25

### Awọn ẹnikọọkan ti o ṣe orire jẹ £10



Aworan ẹniti o wa ni ọwọ osi yi ni Ọgbẹni Dele Awodọla ni o jẹ £3,000 orire ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe laipẹ yi, ẹniti o duro ti ni ọrẹ rẹ Ayọ Arẹmu.

### Awọn ẹnikọọkan ti o ṣe orire jẹ £5



*Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"*


# şile kan pere ra pakẹti 'ASPRO' TITUN yi




# 'ASPRO' nda irora OTUTU-IBA DURO

# Adetọyi sọ ọmọ loruko

KADUNA.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni Ọgbẹni Lasisi Adetoyi ṣe ikomọjade ọmọbirin kan ti Olorun fi ta oe ati iyawo rẹ Raliatu Awero lorẹ. Ona ti esin Musulumi ni nwọn fi ṣe eto isọmọloruko na, nwọn si sọ ọmọ na ni Kuburatu Abakẹ.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Saka Kajogbọla, L. Laloye, L. Adebisi, L. Akangbe Tailor, L. Ajegunlẹ, L. Okuulọla ati Kasumu Adebisi.

Ki Oluwa fi ire ọmọ kari gbogbo wa.

# Tijani sọ ọmọ loruko

IGBOGILA.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu ti o koja yi ni Tijani so ọkunrin ti Olọrun fi ta on ati iyawo rẹ Ramọtu lorẹ loruko Alhaji Sule ni o se eto isin isọmọloruko na, nwọn si sọ ọmọ na ni Abudu Galiyu.

Baba ọmọ na si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ rẹ lọrun. Diẹ kọ 'nu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Kasali Babebeji, Akanbi. Gbogbolowo, Yakubu Akasi, Wahabi Yisusa ati Ẹgbẹ Owolasiki. Ki Olọrun ṣe ọmọ na ni olori ire, ki o si fi ire kari.

# Ẹgbẹ Bọmọde-oku se ẹyẹ ikẹgbẹjade

ONIṢA.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu ti o koja yi ni awọn ọmọ Ẹgbẹ Bọmọde-Okụ ṣe ere ariya eyẹ ikẹgbẹjade ni ilẹ yi. Ogunlọgọ awọn enia ja-nkan-ja-nkan ni o wa si ibi ẹyẹ na lati Ipinlẹ Ariwa, Ila-Orun ati Iwọ-Orun. Ere aṣeyẹ ọjọ na buaiya, o le gongo awọn ọmọ Ẹgbẹ Bọmọdeokụ da bira ni ọjọ na, Ọgbẹni Mukaila Alapala ni o wa ṣere fun wọn nibẹ lati Abẹokuta, irohin ko to afojuba ni; nwọn ṣe ere na lati arọ titi di alẹ.

Ni ọdun 1945 ni agbarijọ awọn ọmọ Yoruba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti o wa si Onitsha lati Oshogbo, Ogbomọsho, Ilorin ati Abẹokuta parapọ d'ẹgbẹ Bọmọde-oku na silẹ si ilu Onitsha lati jẹ iranlọwọ fun tọkunrin tobirin Yoruba ti o wa ni ilu Onitsha ki ere ariya na to bẹrẹ, Ọgbẹni Disu Alamu, ti iṣe Baba-ẹgbẹ na sọ ọrọ iṣiri pupọ nipa bi awọn ti se da ẹgbẹ na silẹ, o si dupẹ lọwọ awọn onile ati alejo ti o wa ba wọn k'eyẹ ariya na.

Lẹhin eyi, Ọgbẹni A Bello, akowe ẹgbẹ na ka oruko awọn oloye titun ti nwọn yan sinu ẹgbẹ na fun ọdun 1960 yi fun gbogbo ijoko. Orukọ awọn oloye na ni:—Disu Alamu, baba-ẹgbẹ, Raliatu Salami, Iya-ẹgbẹ, Samọtu Ayinla, Alaga; Oseni Alade, Gbakeji Alaga ati Lalsi Afọlabi, Akapo. Die ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹi Gbadamoṣi, Alaga Ẹgbẹ Olowolagba. Alli Bello, Alaga Ẹgbẹ Ifẹlodun, Humuani Latundun, Iya-ẹgbẹ Arowoṣaiye. Gbadamọsi Ṣọbalaje ati Sunmonu Adegboye, Alaga Ẹgbẹ Iwajowa.

Ajọ-itu ẹgbẹ o.

# Ẹgbẹ Alakuko

(Lati oju ewe kini)

nipa ete buburu Ẹgbẹ Alakuko, on ni o tu aṣiri iwa-ibajẹ Ẹgbẹ Alakuko na nipa ero buburu ti nwọn gba ninu ipade ikọkọ kan ti nwọn ṣe. Awọn ọrọ ti o ko sinu iwe ifẹgbesilẹ sọwọ si awọn egbe na niyi:—

**"Mo ṣe ikede loni pe, mo fi aye ipo Alamojuto Ẹgbẹ Alakuko (NCNC Field Supervisor) silẹ. Mo si tun yowọ-yosẹ kuro ninu ẹgbẹ oselu na, nko se e mọ."**

"Emi ko ni enikeni sinu. Ohun ti nwọn pese fun mi gegebi Oga-Alamojuto Ẹgbẹ Alakukọ to fun mi. Otalelẹgbeta pọnun (£660) ni owo ti nwọn nsan fun mi lodun kan pẹlu mọto ofe ati awọn nkan anfani miran Ninu ejọ kotụ kan ti o ṣelẹ laipe yi, awọn Ẹgbẹ Alakuko duro ti mi, nwọn si fi owo ran mi lowo lati fi gba Loya. Mo dupẹ pupọ lọwọ wọn fun eyi. Ṣugbọn dipo gbogbo nkan wonyi. Kinise ti mo fi fẹ fi ẹgbẹ na silẹ?"

**"Ṣugbọn nitori awọn nkan iyanu nlanla ti mo nri larin awọn ose diẹ ti o koja ni. Mo ri nkan ewu ti mo si nilati ṣe ikilọ re fun gbogbọ enia ilẹ Naijiria, mo ni ẹri rẹ lowo, mo si fi oju mi ri ewu aitele-ofin ati ibakanjẹ ti awọn Ẹgbẹ Alakuko ti ṣe eto re silẹ nisisiyi, mo si ro wipe, eto mi ni lati se ikilo re silẹ fun gbogbo enia ilẹ Naijiria lati mura sile de e. Gbogbo ẹnyin ara ilu, e kiyesi ikilo mi nitori alafia, ofin ati arisiki. Awọn eniti o ba si feran emi wọn gbọdọ kiyesi ikilo mi".**

"Ninu ipade ti awọn Igbimọ Eto Ẹgbẹ Alakukọ (The Planning Committee of the NCNC) se ni Olu-ibudo Ẹgbẹ Alakuko ni ọjọ kokandilogbon oṣu karun ọdun yi ni Ibadan ni nwọn gbe se ipinnu pe, ki wọn lọ wa awọn fole-folu wa lati Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria ati lati Ghana (Oke-Okun). Ninu ipade na, nwọn tenu mọ ọ fun ara wọn pe, nwọn ko gbọdọ gba awọn ọmọ Yoruba tabi awọn ọmọ ilu Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria si arin awọn fole-folu na, nitori ti nwọn ba je ọmọ Ipinle Iwọ-Orun Naijiria, nwọn ko ni ṣoro fun awọn ọlọpa lati mọ. Nwọntun so ninu ipade na pe, ifura ti awọn ọlọpa ni eyiti o koja ti da iberu si ọkan awọn folefolu ti awọn Ẹgbẹ Alakuko gba si iṣẹ fole-folụ nigbana lati Ipinlẹ Iwọ-Orun, nitorina, nwọn nilati gba awọn folefolu miran lati ilu okere wa fi ropo wọn."

**"Ni akoko yi, awọn Ẹgbẹ Alakuko gba awọn oga-alamojuto ti nwọn yio ma a san owo-giga fun lati oriṣiriṣi orilẹ-ede, iṣẹ wọn ni eto wiwa awọn fole-folu wonpari ati awọn janduku jo, ona meji otooto ni nwọn pin iṣẹ janduku ati wonpari na si. Ni akoko, nwọn nilati ri i pe Ẹgbẹ Alakuko segun dandan ninu idibo welọ Igbimọ Ijoba Ipinlẹ Iwo-Orun ti o mbọ yi. Ekeji si ni pe, nwọn nilati wa ni imurasilẹ gidigidi fun ohunkohun ti o ba le sele lojiji, nitori aibamo bi iru awọn nkan ti Ẹgbẹ Alakuko "ufe ko ba bo si i ma ni gere ti a ba ṣe ajoyo gbigba Ominira Ijoba tan ni ọjọ kini oṣu kewa ọdun yi. Nwọn si fi han gbangba pe, awọn ti ṣe eto silẹ lati dira-ogun fun awọn ehanna ati janduku-enia na dada, nwọn si ti ṣe adehun ifọjukoju pẹlu awọn asoju wọn ti o wa ni ilu okere lati ba wọn ko awọn ohun elo nkan ija na jọ dada.'"**

"Ẹru ba mi gidigidi nigbati mo gbọ lati ẹnu asiwaju Ẹgbẹ Alakuko kan ti o sọ wipe, Ẹgbẹ Alakuko ko le ni ireti lati bori ninu idibo Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria pẹlu awawi tabi awọn nkan aseyọri. Awọn asiwaju Ẹgbẹ Alakuko ti o wa ninu ipade na si taku, nwọn ni awọn ko le fi asodun gba awọn ara-oko ti o ti fi ara mọ ẹgbẹ oṣelu miran pada laijẹwipe, awọn fi agidi-ipa ati iderubani ṣe e. O si

Wo oju ewe kẹrindinlogun



# AWORAN ONITAN

## KINI OBIRIN FẸ JU?

(APA KEJI)

Lati ọwọ M. ỌLALẸYẸ



# Akiyesi Awọn Awo Irawọ nipa Ọjọ-ibi

AWỌN nkan wọnyi ni yio ṣẹlẹ larin ọsẹ yi titi di ọsẹ ti o mbọ June 5-11, 1960.

## CAPRICORN
**(Dec. 21st — Jan. 19th)**

Kinikan ṣẹlẹ ni ọsẹ yi, yio le awọn eto rẹ lere lati gba isinmi ṣere lọ, tabi ki o lọ si irin-ajo. Nipa imọran ti owo, wa a bẹrẹsi ri ere jẹ nipa adehun kan ti o ti ṣe ni nkan bi oṣu meji sẹhin. Itanjẹ diẹ si wa ninu ọran ara rẹ, ṣọra gidigidi.

## AQUARIUS
**(Jan. 20th — Feb. 18th)**

Bi o tilẹjẹwipe ọkan rẹ ndaamu nipa akoko ti o mbọ ni ọjọ iwaju, sibẹ, wa a ri ere pupọ jẹ ni akoko yi. Awọn adehun kan ti o ti ṣe ni ibẹrẹ ọdun yi yio ma a mu owo wa si apo rẹ nipa gbajumọ rẹ. Bi o ba nṣẹju si obirin kan lati fẹ ẹ, yio bọ si i ninu ọsẹ yi.

## PISCES
**(Feb. 19th — Mar. 20th)**

O dabiẹnipe ere wa ninu iṣẹ fun ọ pupọ ni asiko yi ju gẹgẹbi o ti wa fun ọ ninu awọn oṣu ti o kọja sẹhin lọ. Awọn eto ti o ti ṣe silẹ kakiri ni akoko Ọdun Keresimesi ati Ọdun Titun yio ma a ṣe rere fun ọ nisisiyi. Fi si ọkan pe, o ni ọrẹ kan tabi meji, ti nwọn wa ni aye dada laiye yi, ti nwọn si le jẹ oluranlọwọ fun ọ ninu ohunkohun ti o ba de ba ọ.

## ARIES
**(March 21st — April 20th)**

Ṣọra gidigidi nipa wiwa owo kiṣi larin ọsẹ ti o mbọ. Ero ọkan rẹ le tan ọ jẹ lati pa iṣẹ kan ti ko tete mowo-wa ti nitoripe o nwa owo kiṣi. Bi o ba le tubọ rọju fun oṣu diẹ si i, wa a ri i gbangba wipe, iṣẹ kanna yi gan an yio ṣe ohun rere fun ọ.

## TAURUS
**(April 21st — May 20th)**

Gbogbo ọran iṣoro ti o wa ninu ọsẹ yi yio jẹ eyiti o kan iwọ paapa julọ. Bi o ba ngbero lati ṣi ipo pada ni ile rẹ lọ si ile ibomiran tabi nipa ọna onjẹ oojọ rẹ, ṣọra ki o fi ọgbọn ṣe e daradara. Bi o tilẹjẹwipe owo ko si lọwọ rẹ dada nisisiyi, wa a jebo ki o to to ojo Abameta.

## GEMINI
**(May 21st — June 20th)**

Idaamu yio wa fun ilera rẹ fun ọjọ kan tabi meji, yio si ṣilọ kuro. Ninu ọsẹ yi ni wa a mọdaju pe awọn ẹbi rẹ ndi olowo ati ọlọla si i, ati pe o nri iranlọwọ ti o tọ lẹnu iṣẹ rẹ. sa gbogbo agbara rẹ lati ri i pe, o fi idi ọrẹ ṣiṣe mulẹ pẹlu awọn alejo ti o ba ṣẹṣẹ de si ibi iṣẹ rẹ.

## CANCER
**(June 21st — July 20th)**

Akurẹtẹ enia kan wa ni arin nyin, o nilati ṣọra ma a fi ọgbọn ba a lo larin ọsẹ yi. Boya o ti ni anfani kan laipẹ ọjọ yi. Jẹki o tẹ ọ lọrun o. Biotiwu ki aye iṣẹ rẹ ṣoro to, ranti pe, bi o ba le duro dada, ọwọ rẹ yio tẹ nkan ti o nfẹ.

## LEO
**(July 21st — Aug. 21st)**

Ni itẹlọrun ki o si ṣe akiyesi dada ninu ọsẹ yi, ki o ma si ṣe fi ikanju yi ipo pada ni asiko yi. Biotiwu ki wahala ilẹ pọ fun ọ to ni suru fun igba diẹ. Titi ipari ọsẹ, wa a tubọ no owo lọwọ si i, wa a si mọ awọn ti o jẹ ọrẹ rẹ ati awọn ti o jẹ ọta rẹ yatọ.

## VIRGO
**(Aug 22nd — Sept. 22nd)**

Iṣẹ ti o wa fun ọ ninu ọsẹ yi ni lati ṣa awọn ojulumọ rẹ jọ si ọtọọtọ. Ọpọlọpọ awọn enia ni o ti nwa ba ọ ṣe papọ, ṣugbọn ọkan tabi meji ninu wọn ni o dabiẹnipe wọn fẹ jẹ ọrẹ ododo si ọ. Titi ipari ọsẹ yi, boya wa a ti darunpin wipe, o kuku san ki o fọwọ modi ọrẹ atijọ kan.

## LIBRA
**(Sept. 23rd — Oct. 23rd)**

Boya o ti nṣe iyemeji lori eto bi owo yio ti ṣe nwọle fun ọ ni akoko ti o mbọ. Ọkan rẹ yio tubọ ma a balẹ siwaju ati siwaju si i nipa awọn eto ti o ti ṣe fun iwọn asiko yoku ninu ọdun yi. Wa a si ri iwe kan gba ti yio fi ọkan rẹ balẹ pe on si ni igbagbọ si ọ, yio si ran ọ lọwọ. Alfaiyabalẹ ile yio si wa fun igba diẹ.

## SCORPIO
**(Oct. 24th — Nov. 22nd)**

O ko ni i gbadun iṣẹ rẹ dada bi ti atijọ. Enikan ti o ti da ijọngbọn silẹ ni ijọsi ti tun bẹrẹ ijọngbọn rẹ na. Sibẹsibẹ na, ireti mbẹ fun ọ ninu ọpọlọpọ ileri ti nwọn ti ṣe fun ọ, gbogbo iṣoro ti o si wa fun ọ lode ni wa a yanju rẹ patapata nipa awọn iṣẹ titun tabi iṣẹ titun ti o fẹ gba.

## SAGITARIUS
**(Nov. 23rd — Dec. 20th)**

Gbogbo nkan wọnyi yio dọgba fun ọ ninu ọsẹ yi bi o ba le faramọ awọn akurẹtẹ-enia titun kan ti nwọn ṣẹṣẹ de si arin nyin. Bi o ba fẹ lowo-lọwọ, ki o si wa ni aye ipo ti o wa nisisiyi, o nilati faramọ ilana kan tabi meji. O nilati lọ sinmi a nwa obirin kakiri tabi a nda pade-npade pẹlu obirin kakiri fun igba diẹ na.

## Awọn danadana da awamọto kan lọna

UMAUHIA.

NI ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu ti o kọja yi na awọn danadana da awamọto kan John Okoye ẹni ọgbọn ọdun lọna larin ọna Umauhia ati Okigwi. Irohin ti awamọto na fun awọn ọlọpa nipe awọn ọkunrin mẹta kan wa ba on ni ilu Umauhia pe ki on wa fi mọto on gbe wọn lọ si Okigwi lẹhinti nwọn ti duna-dura tan, ni awamọto na ba gbe mọto rẹ o si doriko ọna Okigwi, ṣugbọn nigbati nwọn ti rin ibuso mẹta ati abọ ni ọkan ninu awọn ọkunrin na ni on fẹ yagbẹ, awamọto na si duro fun un.

Lẹhinti ọkunrin na ti bọlẹ tan ni ekeji na ba tele e pẹlu ibọn lọwọ, o si da oju ibọn ọwọ rẹ kọ awamọto na, ẹkẹta wọn si fa a jade lati inu mọto; nwọn si bi i lere pe ewo ni o fẹ yalaa ki o fi kokọrọ mọto rẹ silẹ ni tabi ki awọn pa a, ọkan ninu wọn si fun lọrun pe ki o ma bale kigbe. Esẹkẹsẹ ni o ti fi kọkọrọ mọto rẹ titun na silẹ, ni awọn danadana na ba gbe mọto na salọ. Pẹlu omije loju ni on ati awọn ọlọpa fi nwa awọn danadana na kiri.



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ni o duro larin ninu aworan yi ti awọn aṣiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre si rọgba yi i ka nigbati Ọgbẹni S. G. Ikoku, Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun nki wọn ku abọ ni ibi ipade ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ni ilu Kalaba laipẹ yi




# Nurse Harvey's GRIPE Mixture

Egbogi apolu fun inu-rirun ti NURSE HARVEY'S GRIPE MIXTURE jẹ eyiti awọn abiamọ ti nlo lati adorin ọdun sẹhin ti o si nṣe iwosan pelu iyanu, ko lewu rara, bi a ba si nfun ọmọde mu deede ko ni jẹki arun inu-kikan, inu-iwọ ati inu-kikonl, a ma a jẹki ọmọde sun dada lati igbati nwọn ba ti bi i. Bi a ba nfun ọmọde mu lekọokan yio jẹki o ni ilera ki o si ma a yagbẹ dada ni gbogbo asiko ti o ba wa ni ọmọde.




HARVEY-SCRUTON LIMITED · YORK · ENGLAND

